**Lakaye Oro**

Igba laiye, bi aiye ba ja ko se mu so Ẹni bi mọ ti ko mọ iwe tabi ẹkọ ina jo, tabi ko jo, ai mọ we nje niya kiyesi iwọ fẹ otitọ ni inu, ati ni inu ikọkọ ni iwọ yio mu mi mọ ọgbọn ọgbọn nki gbe kiri ode

# IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ .DE, OKUNKUN PARADA.

**Wanted**

Advance Apprentic Compositors
Apply in Person:-
POPULAR PRESS
6, Ojo Road,
Odu-abọrẹ Mushin

VOL. V No. 320 MONDAY MARCH 12 — MARCH 18 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# IYAWO MEJI KỌ OLO-WOLAGBA, O POKUN SO

NI ITOSI IGBARA ODO NI EKITI NI ỌGBẸNI OLOWOLAGBA TI SO NI ỌJỌ KỌKANLA OṢU KỌKANLA ỌDUN TO KỌJA. NI ỌJỌ YI, ON ATI ỌMỌ RẸ OLOWOLAIYEMỌ NI O JỌ LỌ SI OKO.

Ọmọ ọdun mejila ni olowolaiyemọ iṣe marun dinladọta si ni baba rẹ o ni nigbati on ati baba on hu iṣu tan baba on bọ si nu oko koko nibiti wọn ti ri nigbẹhin lẹhin ti o ti so.

Niwaju Ọgbẹni Afọlabi Fagbemi ẹniti ijọba yan lati wadi ohu ti o ṣe Olowolaiyemọ ti o fi pokun so, ara ile rẹ, Ọgbẹni Francis Adeọla ni lati ọjọ ti iyawo mejeji ti Olowolaiyemọ ni ti kọọ silẹ ni inu rẹ ti bajẹ, ti ọkan rẹ si ti daru o ni eyi tun buru si nigbati awọn alayin si tun nyin si ọrọ na Osi ro pe eyi ni o mu Olowolaiyemọ pokun so. Ọgbẹni Afọlabi ni on ni igbagbọ pe Olowolaiyemọ pokun so nitoripe ọkan rẹ bajẹ ni.

O fun awọn obirin ni imọran lati ma ro igbẹhin ohun ko hun ti wọn ba nṣe ki wọn to maṣe o ni ọpọlọpọ ipar ẹni ni oti tipasẹ obinrin ṣẹ o ni idakeji ẹwẹ ti ọkun rin ko ba ya ọlẹ o yẹ ki o mọ pe ti aya kan ba fi on silẹ ti iṣẹ ba wa lapa ti owo wa lọwọ on le ni pupọ dipo rẹ Nitorina aya kọ ko to ohun ti a ntori rẹ pokun so.

## Iwadi nipa Owo Ile-Iwe giga ni Iwo Orun

Ijọba Iwọ Orun ti yan enia mẹfa lati ṣe iwadi nipa owo Ile iwe giga ni Iwọ Orun. Ni ibẹrẹ ọdun yi okiki kan pe ọpọlọpọ Ile-iwe giga fi kun owo ile iwe won.

Awọn miran ni nitoripe Ijọba na fa ọwọ sẹhin lati fi owo silẹ ni. Ṣugbọn Ijọba fi ye wa nigbana pe ohun ti awọn ri ni pe bi wọn ti nṣe iranlọlọwọ to awọn Ile-iwe giga miran tun ngba ju iye to yẹ lọ lọwọ Obi. Nitori eyi ni awọn ṣe ṣe ofin titun, awọn ko si fẹ ki ẹnikẹni fi kun owo Ile iwe mọ.

Awọn ti Ijọba yan si Iwadi na ni Ọgbẹni Ajayi, Omidan Bọla aya Awẹ, awọn mejeji olukọ nile ẹkọ giga Unifasiti ti Ibadan, Ọgbẹni Maduenipi ti Bini, Ọgbẹni S. A. Thomas, A O. Adetọla, ati E. O. Babatunde.

## Odun kekere itunu Awe dun pupo



Awọn ti a nwo ninu aworan [illegible] Ijọ Mosa[illegible] ilu Eko nigbati awọn nkirun Ọdun kekere itunu Awẹ (Eid-el-fitri) ni ita tẹju Ọbalende lọjọ Alamisi nigbati nwọn kọkọ gbe irun ọdun duro, awọn Alufa ati awọn Ijimi enia ti o mbẹ niwaju aworan yi ni, Alhaji Liadi Ibrahim ti iṣe Lemọmu Jamiyu ti ilu Eko lo duro ni iwaju ti wọn ṣe ọna si ara Alikimba rẹ. Awọn ti o duro lẹhin rẹ ni lati ọwọ ọtun, Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji, on lo ko Ilẹkẹ Iyun kọrun, lẹhin na ni Oloye Ọjọn, ati Lemọmu Nuraini ti Mọṣalasi Ita Balogun.

# ỌRỌ OLOTU

## SISAN NI OWO ORI

Ni ibiti a laju de yi, ko yẹ ki a ṣẹṣẹ ma bẹ ara wa ki a to ma san owo ori, o ti pẹ ti owo ori ti wa; gbogbo wa ni a si mọ ohun ti a nfi owo ori ṣe. Papa ni aiye isiyi ti ilọsiwaju ngun ori ilọsiwaju, o yẹ ki a mọ pe bi owo ori ba ṣe nwọle si bẹni ilọsiwaju yio ma de si, Ile iwe ọfẹ, itọju aboyun ati itọju ọmọ ọwọ, ati ohun bẹbẹ ni a nfi owo ori wa gbọ.

Nje o ha yẹ nigbana ki a ri enia ti yio ma sa lati sanwo tabi ti ko ba fẹ san rara? Awọn kan wa ti ki ifẹ san, awọn kan wa ti nwọn ki isan to iye ti o yẹ, awọn kan si wa ti nwọn ma nsa kiri. Ninu gbogbo awọn wọnyi ko si ẹniti o fẹ ilọsiwaju ilu, nitori laisi owo ori, o daju pe ohun kan ko ṣe ṣe. Ni ọsẹ kẹta sẹhin ni awọn obinrin Eko ko ara jọ pe awọn ko fẹ san owo ori. Ni ọsẹ to kọja ẹgbẹ Osiṣẹ kan gbe wọn lẹṣẹ. ohun buruku gba ni eyi, nitoripe ẹgbẹ yi ko sọ otitọ ohun ti o wa lọkan Ijọba tabi bi Ijọba ṣe fẹ yọ ori na.

Ijọba ko ni gba owo ori lọwọ gbogbo obinrin, obinrin ti o ba ni to ti gbogbo aiye si mọ pe o ni, ni Ijọba yio gba owo ori lọwọ rẹ, kini ṣe ti awọn obinrin Eko wa nkigbe? Nisisiyi gbogbo obinrin ti o nṣiṣẹ labẹ Ijọba ti owo ọdun rẹ ba ti to apo mẹta ni o nsanwo ori. Pupọ ninu awọn obinrin Eko ni o ni mọto, ile ati ile itaja nla ti nwọn si ni bi apo mẹwa si mejila ni Ile Ifowopamọ.

Ṣe nibiti obinrin to ngba apo mẹta lọdun ti nsanwo ori ko yẹ ki iru obinrin bayi san? O yẹ ki ẹgbẹ T. U. C. ro ti Ọlọrun bi nwọn ba nfun awọn alaimọkan ni imọran. Akoko ti obinrin ki isan owo ori ni akoko ti obinrin ko ni ṣe lapa, ti o jẹ wipe ọkọ lo ngbe gbogbo ẹru, ṣugbọn nisiyi ti obinrin nkọle mẹfa mẹjọ, ti obinrin nra mọtọ mẹta, marun, o yẹ ki nwọn san owo ori ki ilu le tu gbogbo wa lara. Imọran tiwa ni pe ki Ijọba sa gbogbo Ipa wọn lati ri pe awọn obinrin to tan, to ni lọwọ nikan lo nsan owo ori, ki nwọn si tun ri pe gbogbo ẹnikẹni ti o ba yẹ ki o sanwo ko yọ pọrọ mọ. Sisan li owo ori, ẹ mi jẹ ki a sa iṣẹ wa ti, ṣiṣe ni.

---

## Asoju ile Meka ati Israeli lo si Mosalasi



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni igbati awọn Musulumi Eko gbe irun duro lẹkeji ni Mọṣalasi Ọdun, awọn ti o jẹ enia pataki ninu aworan yi ni Alhaji Shaki on lo duro lẹhin o ni fila dara ti a nwo ori rẹ niwaju. Aṣoju ilẹ Larubawa (Ambassador U. A. R.) lo ta okun dudu mọ ori, lẹhin na ni Aṣoju ilẹ Israeli (Ambassador Jordan) lo fi jingin dudu si oju.

## Lati arisun oku de ajule orun

Ni oru ọjọ aje ni ọsẹ tokọja ni mọto pa Ọgbẹni Johnson Adeniji nigbati o nbọ lati aisun oku alufa Adeola Adebọgun.

Opopo Adam ni igborọ ilu Eko ni ọgbẹni Adeniji ngbe, on pẹlu iyawo rẹ ni o si jijọ lọ si aisun, bi nwọn ti nbọ lati aisun ti nwọn de fayawọ ni mọto kan kọlu Ọgbẹni Adeniji, o ṣubu lulẹ o si ku.

Nibiti nwọn ti nreti Ọlọpa oni mọto miran de, o si tun gun ori oku na laimọ. Ọmọ Ọgbẹni Adeniji ni totọ Baba on dagba to lati ku, ṣugbọn ki iṣe iku oro ni o yẹ.

---

## A fi ipile Imọran fun 'awon ti won nsowo labe U A C lele

Eto ti awọn ẹgbẹ onisowo U. A. C. ti ilẹ Nigeria nṣe lati da Iranlọwọ fun imọran awọn Onisowo" ni ao fi idi rẹ lelẹ kakiri ni ilẹ Nigeria ninu ọsẹ tokọja. Ni ila orun ni Port-Harcourt, ni iwọ orun Ibadan ati ni olu ilu Eko, ni awọn ẹgbẹ onişowo yi ti nṣe eto ipade apa pọ fun nkan bi ọjọ meji tabi mẹta nibiti jẹ wipe ọpọlọpọ a wọn onişowo jankan-jankan ni wọn yio pe sibẹ.

Ninu ipade nwọnyi ni awọn onişowo Ọkunrin ati Obirin ti wọn ti ni aṣepọ pẹlu ẹgbẹ onişowo yi yio ni anfani lati le sọ nipa bi oti ṣee ṣe, pẹlu ọna ti tun iṣọ owo ṣiṣe fun anfani wọn pẹlu ogbologbo aṣoju awọn onişowo U. A. C. ti ilẹ Nigeria

Ni ilu Eko, Ọgbẹni J. B. Davies, O. B. E., ti nṣe alaga onişowo yi ni o si ipade na ni ijọ Alamisi ọjọ kini oṣu March 1962 ti Ibadan bẹrẹ ni ijọ Jimọ ọjọ keji oṣu March 1962, ti awa bẹrẹ ipade na ni Kano lẹhin tunu awẹ ni ọjọ kejila oṣu March 1962, Ipade kini ti ila orun bẹrẹ ni ijọ alamisi, ni ọjọ kini oṣu 1962, Ninu ọpọlọpọ ohun ti a sọrọ lori rẹ ni awọn na ọja tita titun ipolowo ati bi o ti nrau awọn ti o nta ọja lọwọ, tito ohun ọja si ori atẹ, owo ọja, ohun elo ọja, ati itọjuto ọja awin ati itọna fun ọja tita.

---

## Bar ka-de Salar E ku Odun

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## IRE TO WA NINU IBI

LATI ỌWỌ:— AKIN ỌLA BURAIMỌH
NO. 133, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ko si ohun to wa laiye ti ko sọna ire ninu nwọn. Bi ibi ba pọ lapọju ti o mu ọkan rẹ mọ ibanujẹ, ma a dupẹ lọwọ Ọlọrun to da ọ, ẹ wo ẹniti o fo sanlẹ ti o si ku, aiye a pe ibi nla de si wọn, ṣugbọn bi ko ba ku, bi o di were nkọ? ti o nja kiri bi nama, ti o si di abugi jẹ, kini ka sọ siru o ni yẹn.?

Bi o si ni were li enia, ranti pe Ọlọrun ṣ'ẹgbọn, o ku ohun to tun buru ju asinwin lọ. Tabi o ko ri ọmọ enia to di adẹtẹ, to si ge lọwọ, ti aiye nsara fun nile loko, Oluwa ki o ma fi arun yọ wa lẹgbẹ, Ẹtẹ ki sa mbo enia, ko tun ma yan larin ilu, Se a ri asinwin to nyan fa-nda ka ile kiri.

Ki a si tun ro ida keji wo, ki a wo ire ti ibi si tun nmu wa, a o rii pe ibi kun fun ire. Ṣe bi oku ba ku a o si gbẹ sare, ẹni to gbẹ a rowo ra ohun jijẹ ati ẹniti o kan posi na pẹlu. A rowo rẹ wu a kanpọ; Ogun si tua mbẹ fun ọpọlọpọ lati jẹ, nigbati iwọ si saisan, ṣe o tun pe Dokita wa sile, o sa gba owo ko to ṣe ohun ko hun.

Ẹ wo ọpọ enia ti nwọn nṣe oniwosan laiye, ki a bi wọn kini nwọn njẹ? njẹ ti ẹda ko ba saisan, iru nwọn yio ṣe lowo lọwọ? ki nwọn kọle, ki wọn laya, ki wọn ra mọto, ki nwọn di enia atata.

Ẹ si tun wo Lọya ọgọrọ ti nwọn ngba ẹjọ ro ka, ki a bi wọn kini nwọn njẹ, bi ẹda ko ba lu ijangbọn kini yio gba Lọya fun? Ṣe inu kejọ ba owo araiye, ni nwọn gbe njẹun, ti wọn nrowo se ohun giga-giga, tọwọ wọn nwọwe lonre ilu okere, ti wọn ndẹni ti o nlorukọ laiye gbogbo.

Ki a si tun wo Alufa, ti wọn wa laiye, ki a bi nwọn iṣẹ ti wọn nṣe, njẹ bi ilaju ba pọ kari, ti gbogbo aiye ba mọ Ọlọrun, ti ko si keferi, ti ko si abọrisa mọ, kini ki Alufa tun wa laiye fun, tabi tiṣa to nṣe o nitọna wọn? ṣe iṣẹ ka la ni loju ni on nṣe, ka fẹkọ Olodunmare kọ ni, ki a le tọ ọna atata, ka ye ṣe bi ẹranko ninu aiye gbogbo.

Ki a si tun ro ọna miran kini a o ri bi ire ti o nti inu ibi yọ, ẹ wo ogun to ja to si fọ aiye loju. ka ronu kini ire ti o ṣẹ fun wa? ṣe ọpọlọpọ imọ ijinlẹ ti o wa ni kọkọ ni ogun to ja fa wa saiye, ti o dohun to dara fun gbogbo wa, ọkọ to nrin loju sanma nkọ? ṣe ogun lo mu de inu aiye wa.

Pẹlu-pẹlu ki a wo ọpọ enia ti wọn nṣiṣẹ ogun ninu aiye gbogb, ọgọrọ awọn wọnyi lo ti nṣe ọsọlẹ, nigbati ko siṣẹ ri. Ogun de o sọ wọn dẹni nriṣẹ ṣe, ọpọ enia lo si tun wa, ti iṣẹ ogun sọ wọn dọga, ti wọn doloye ti aiye mọ gbogbo, ti wọn dẹni nilari loju ẹnikẹni, Bi ogun ba si pẹhin da, ṣe alafia yio bọ de, a o fohun to lọ kọgbọn gbogbo, Alafia yio wa fun gbogbo Orilẹede, Olikaluku a ma ri ibi yan.

## Awon Onise gbagimole



Awọn ẹni meji ti a nwo nwọnyi ni awọn ọmọ ilẹ Naijiria [meji ti wọn lọ kọ iṣẹ gbagimọlẹ ni ilu Oyinbo orukọ wọn ni wọnyi:- Ọgbẹni James Obonna, lo wa lọwọ ọtun ati lọwọ osi ni Ọgbẹni Reymond Eiekukọ.

## OWE AKA RERIN

Lati Ọwọ:- GABRIEL FUNSHO AFỌLAYAN
No 305 ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

1. Eni amọri ibaku amọri alara iba kosi kanga Kokumọ pẹlu Iya rẹ si ma ku
2. Iduro ko si bẹni ibẹrẹ kosi fun ẹniti o gbe ọmọri odo mi
3. Agbẹ to fisu sodo lodija silẹ, bibẹkọ, ọmọri odo ko nlu Iya rẹ lasan.

EGBOGI
## 'CHLORODONT'




Bere Egbogi Jamani ti osesẹ de fun ẹnu rirun tabi 'EHIN ẸNU ti o ba nyọ tabi kika fun ara rẹ, eyi ni a ma npe ni OMURỌ EHIN. Kokoro ni o ma ngbẹ tabi jẹ idi Eriki na, a si ma jẹ ki ẹnu ma run tabi ṣiyọn bibajẹ pẹlu. Pa kokoro buburu yi run pata-pata mpa lilo egbogi ti wọn npe ni CHILORODONT DROPS.

Igo nla:- Silemeje-abọ pere 7/6
Igo kekere:- Silemẹrin pere 4/
OWO ỌKỌ Silekan-abọ (Postage 1/6d)

BERE FUN



Ojulowo Egbogi ti npa EKUTE bi mọnamọna laini ewu rara fun enia tabi ohun ọsin miran ni ile.

Silemeji pere ni (2/-) Dọsini (£1)
OWO ỌKỌ:- Silekan-abọ (Postage 1/6d)

Bere Egbogi wọnyi ni ṣọbu awọn

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

AKIYESI:— Ri daju gbamgba wipe ṣọbu ti wọn nta lo gbe ranṣẹ lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọta adamọdi tabi orisi omiran fun ọ o, maṣe gba rara.

# Yẹyẹnatu!

## ONIYẸYẸ EKO!

### YẸYẸNATU APA KEJI ỌRỌ RẸ PẸLU OLOTU

Olotu: Yẹyẹnatu, obinrin mẹta, o ma ṣe ẹ si

Yẹyẹnatu: Ṣe mo ti sọ pe mo nlọ pari ija Suberu ati Adija.

Olotu: Bẹni, beni. Ṣe o si ti ba wọn pari rẹ?

Yẹyẹnatu: Ọrọ ma pọ ninu iwe kọbọ nigbati mo de ọdọ Adija. Bi Suberu ṣe ro ejọ bẹ ni on na wi, o wa bi mi lere, o ni Yẹyẹnatu!, bi o ba ṣe bi Olu ṣe nde mi mọlẹ ni yẹn, ojẹ ngo de ọdọ tirẹ?

Olotu: Ha! o sọ yẹn tan!

Yẹyẹnatu: O ni nma da lohun o jare, o ni o ti ri Iyawo ti ko gbọdọ Jaiye mọ niyẹn. Bo ya nwọn ko sọ fun pe ọmọ Jaiye jaiye li on ni.

Olotu: Nibo ni ẹ sọ si nisisiyi tabi bẹ ni yio ṣe fi Suberu silẹ patapata?

Yẹyẹnatu: Mo bẹbẹ pe ki o dariji Suberu, o ni on ni ifẹ rẹ pupọ, on ko si kọ lati pada ti o ba le pinnu lati ma mu oju kuro. O ni o yẹ ki Suberu ti mọ pe ẹnikẹni to ba fẹ gbajumọ yio moju kuro ni.

Olotu: Lotọ si ni Kofo gbajumọ nitori ko si ibiti nwọn ko mọ Koforun. Ha-ha-ha tabi mo purọ?

Yẹyẹnatu: O de niyẹn, ẹ ti lẹ farabalẹ.

Olotu: O dara ma binu. Ṣe o si ti pada si ọdọ Suberu?

Yẹyẹnatu: Rara! O ni lẹhin ọdun awẹ ni on yio pada.

Olotu: Kini wa ṣe ti o jẹ lẹhin ọdun awẹ ni yio to pada?

Yẹyẹnatu: O ni on fẹ duro gba ti ọwọ Olu on si ti sọ fun pe, on ko ni pada sọdo Suberu mọ, on si ti nṣe onjẹ awẹ. Ninu ọdun Olu ti sọ fun on pe on yio ra aṣọ ọdun fun on.

Olotu: Iwọ si ro pe Olu yio ra a nitotọ?

Yẹyẹnatu: Yio ra fun.

Olotu: Mo ṣebi o ti fẹ Iyawo miran lẹhin ti Adija fi silẹ lọ fẹ Suberu?

Yẹyẹnatu: Hẹn. Lotọ ni. Ṣugbọn lati igbati Adija ti kuro lọdọ Suberu ni ko ti fi owo onjẹ silẹ mọ fun Iyawo rẹ.

Olotu: Ha! o ri ẹni atijọ, o gbagbe tile, o maṣe o!

Yẹyẹnatu: Ẹ ṣe gan ni. Ṣe ko mọ nisisiyi pe Adija yio tun ko ẹru lọ.

Olotu: Ọkunrin miran ma ya olori buruku o. Iyawo ti o nbimọ fun u ko tọju rẹ, eyiti o nṣe ọmọ jaiyejaiye lo nkowo fun

Yẹyẹnatu: Ori rẹ lo buru. Iru wọn pọ ṣa o.

Olotu: Ẹnyin obinrin na kọ ni ẹ nfa. Tabi ọkunrin wo ni o ma ri ọyan yin lati inu buba tabi Itan obinrin ni oju titi ti ara rẹ ko ni sọji?

Yẹyẹnatu: Ẹ jọ yin ni yẹn. Bi o ba ṣe wu wa ẹ jẹ ki a mura wa. Bo wu wa a, a wọ pata rin. Ilaju lo de ni obirin nrin ihoho ni Eko. Ohun to ba wu Alara ni nfi ara rẹ nṣe.

Olotu: Ṣugbọn ṣa Ọla ni ọran, ara ni yio fi abọ si.

Yẹyẹnatu: Ẹ ṣe. O digba, o tun di ọsẹ ti o mbọ. K'Oluwa ma kọ atunri.

---

## Irohin Imole di Araba

---

## Obinrin je Oye Premier nile India



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Iyafin Sirimawo Bandaraiko, on si ni Olobinrin ti o kọkọ jẹ ọmọ Ẹgbẹ gbogbo agbaiye nitoripe aṣiwaju awọn Oṣelu Ceylon nise ọmọ rẹ ọkunrin loduro ni ẹgbẹ Ọgbẹni Duncan aṣoju ilẹ Gẹsi to wo pade rẹ loduro lẹgbẹ ọmọ rẹ.

---

## Omode yi nluwe ninu omi Iye



Obinrin Oyinbo ti a nwo ninu aworan yi jẹ Aladura, okiki rẹ si ti kan nipa omi Iye ti o ma nṣe fun gbogbo awọn ti o ba wa fun Iwosan kakiri Ilu London, Ọmọ enia dudu ti a nwo yi, baba rẹ Ogbẹni Thomas, Nigbati nwọn de Ilu oyinbo efufu buruku fẹlu ọmọ na, ọwọ kan ati ẹsẹ kan si rọ baba rẹ Thomas gbe ọmọ na lọ si Orthopaedic nilu Wales, Ṣugbọn Iyafin Barnet Aladura, sọ fun baba ọmọ na Thomas pe ki o lọ mu ọmọ rẹ kuro ni Orthopaedic wa sile on,

Lararọ ni Iya aladura yi ma nṣe omi iye fun ọmọ na lati ma fi wẹ Ni owurọ ọjọ yi ni ọmọ na fi han Iya aladura na wipe ki o wo o ọwọ on ti o ti rọ pada bọ si ipo rẹ Iya aladura na wo osi nrẹrin ayọ.

## Ore Aiye kilo ja mo?

Ẹ jọwọ ẹ ba mi gbọ ọrọ yi anu aṣeju lo nbi gbese nitoripe ọmọ araiye ko mọ ohun rere, eke ni wọn, abanijẹ lọmọ araiye, Emi lo wa ni bẹ, ara to ba wun mi ni ngo da, ko yẹ ọmọ enia ewu ni! ọran ni! iku si ni pẹlu, Bi oluwa rẹ ko ba ku si ọrun yio ku si ra bi iṣu.

Ọga oniṣẹ Ijọba ma ṣe iṣẹ ika si enia ore loyẹ ka me wa fun ara wa ko yẹ ka ma wa ọta nitori ọrẹ araiye yi ko nfẹ rere fun ẹnikeji rẹ, afi „Ibanujẹ ati oṣi Oluwa nikan lo yẹ ka gbagbọ.



WOLI KOGBEREGBE

Olododo kan ki ṣegbe, nitope ko si Ibi kan ti yio ba olododo, ṣugbọn awọn enia buburu ni yio ku ti ki yio si atunṣe. OWE 12 ẸSẸ 21. ohun rere kan ko si fun aṣiwere, Enia to ba gbọ ti Ọlọrun oju ko ni ti wọn, Enia to ba duro ti Oluwa koni ṣe aisan bẹni koni padanu bẹni koni ri idi ibajẹ, yio ṣora fun enia buburu ko to ri oju rere Oluwa ohun rere kan kosi lọdọ enia bi ko ṣe ibi ati eke.

Fi e t i si ohun ẹkun mi Ọlọrun mi nitoripe ni ọdọ rẹ le mi yio ma gbadura si nitori ti iwọ ki ṣe Ọlọrun ti nṣe inu didun ṣi iwa buburu bẹni ibi ko le ba ọ gbe awọn agberaga ki yio le duro niwaju rẹ, Ọlọrun korira awọn oniṣẹ ẹṣẹ yio pa awọn ti nṣo eke run Ọlọrun korira awọn ọni eke ati enia ẹlẹtan ko si otitọ kan lẹnu awọn ọmọ enia PSALM5, ẸSẸ 2. Enia oke ati ẹlẹta, ati abanijẹ lo pọ nilu Eko Agbalagba wọn to jẹ obinrin nwọn kiri ile ọkọ ọmọ wọn ndọkọ iya si bẹrẹ si ṣe pansaga, Awọn obinrin to ti darugbo ni ilu yi gbogbo wọn ni wọn nṣe agbere kiri bi aja, aja ko se agbere to ọpọlọpọ ninu wọn.

Obinrin to wa ni ilu Eko nṣe fari ẹgbẹ, nwọn loyun iyangbo nwọn si mbi efufu jade emi yio dabi na ti yio jẹ yin run. Kiyesi o nrọbi ẹṣẹ osi loyun iwa ika osi mbi eke jade PSALM 7 ẸSẸ 14. Ẹmase jina si Ọlọrun ki iwọ le sẹgun ọta rẹ ile aiye yi kose fi agbara jẹ, nitorina gbogbo ẹnyin alagbere ẹ fi ẹsọ jẹ aiye bi aiye ba ja kose so.

---

## Gbanjo! Gbanjo!

O MA NLỌ GBANJO!!!

A fi eyi kede fun awọn onibara wa jake jado Naijiria ati Ghana pe, a o bẹrẹsi ta awọn ọja gbanjo wa lati ọjọ karun oṣu yi titi di ọjọ keji oṣu to mbọ. (5/3/62 - 2/4/62) nitorina aye wa fun olukuluku nisisiyi lati ri ọja rẹ ra ni ọpọku ọyọku. lẹhin asiko ti a fi sinu iwe yi, awọn ọja na yio pada si iye owo wọn.

Iwe egbogi Ajẹbidan Agbabiẹtu 25/- tẹlẹ di 22/-
Iwe Gbedegbẹyọ Hausa ṣile mẹta 3/ tẹlẹ di 2/-
Iwe Ala ati Iwadi nkan 3/6d di 2/6d
Turari Ajẹbidan fun ẹyọnu ajẹ ati itaja 10/6d di 7/6d
Idaji Pangolo Turari Ajẹbidan 8/6d di 5/6d
Idamẹta 4/6d di 3/-

Fun anfani awọn ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ - Orun Naijiria ẹ wa si ọdọ:-

MANAGER 6, OJO ROAD ODUABỌRẸ MUṢHIN

Wọ Bus Oṣhodi ki o sọkalẹ ni Bus Stop Muṣhin nibiti nwọn gbe nta Iṣu tutu. Bere Way Street ti o ba tọ ọ de opin, bere 6, Ojo Road, iwọ yio si ri ile iṣẹ wa.

Fun anfani awọn ti o ngbe Eko, lọ si ọdọ:-

LATIFU, 16, BAMGBOṢE STREET LAGOS.

## SEBOTIMO (APA KEJO)

Lati Ọwọ:- FUNMILAYỌ KOFOWORỌLA

Iwuri ni o jẹ fun mi nigbati mo ri ka ninu iwe Irohin imọlẹ n pa iwe ti Timọti Lijọka ọmọ Okitipupa kọ si olotu pe Itan Ṣebotimọ dun pupọ itan na ṣeṣẹ nde ibiti o dun gan nisisiyi mo si ro wipe ẹnyin oluka itan mi yio tọju kọbọ meji silẹ lọsọsẹ fun rira iwe Irohin Imọlẹ lati le ma gbadun itan mi oloyinmọmọ na, itan mi ọsẹ yi bẹrẹ nibiti wọn ki Nini owo mọle, ki wọn fi le ri di pe on ni o fun Iranṣẹ Ọmọbinrin na loyun, oyun yọ gedegbe lara Iranṣẹ Ọba Obinrin na ni oṣu kan nigbati Ọba ri pe oyun na yọ gedegbe lara Iranṣẹ on, o pe gbogbo ẹmọwa rẹ jọ o ni alejo nla ti agba si ilu yi o ti fun Iranṣẹ binrin mi loyun, ewo ni siṣe o gbogbo wọn si da lohun pe pipa ni a o pa awọn mejeji, Ọba binrin na si dahun ki a to da ẹjọ Iku fun enia o yẹ ki a gbọ tẹnu rẹ, nitori idi eyi ẹ lọ de awọn mejeji wa tọwọ tẹsẹ siwaju mi.

AWỌN IKỌ DE WỌN TỌWỌ TẸSẸ SIWAJU ỌBA.

Nigbati orun kan atari ni wọn di awọn mejeji, wọn si ru won ni odondoro wa siwaju Ọba, bi wọn ti sọ wọn kalẹ tan ni onifere Ọba ba fun fere lati le jẹki odi mimọ fun Ọba pe, wọn ti ko awọn Arufin na de, bi ọgan ni ọba wọn jade sita pẹlu ẹmẹwa rẹ. Wọn ba si bere lọwọ Nini owo pe:—

Ọbabinrin:- Kini o sọ wipe ọ gbe ọ dehin?
Nini owo:- Emi ati awọn ẹlẹgbẹ mi jijọ nlọ si ilu ogun ni.
Ọbabinrin:- Olubode ko ha ti ka ewọ fun nyin ki ẹ to wọ ilu yi.

Nini ọwo-: Kabiyesi ko ka ewọ kankan fun wa.
Ọbabinrin:- Ireke lo wa na iọja ọmọ ẹra ha ṣe denu igba owọlu taiwọlu o fun obinrin loyun iwọ ko mo pe ẹnito ba ṣo ru eyi pipa ni a npa ni ilu wa

Nini owo:- Obu sekun gba a oni kabiyesi Ọba alaye luwa alaṣẹ ikeji orisa, bayi lanṣẹ ni ilu wa ewọ ibomiran tabi bi a ba obinrin sọrọ ni ilu wa nipa ọrẹ yiyan ti o ba si gba, akin tun wa idi rẹ wo pe o dijọngbọn si ni lọrun bi basọ ti mo ba sọ ti o gba lo mu mi ṣẹ si ofin yin ẹdakun ẹfori jimi nko ni ṣeru rẹ mọ lailai

Ọbabinrin:- Ọbabinrin na yiju si awọn ẹmọwa rẹ oni, ṣe ẹnyin na gbọ idahun ti alejo yi dahun ko yẹ ki a ma fa ọrọ gun lọ titi ẹṣẹ amọmọ ko ni aforiji bi ko se ẹṣẹ ti enia mọmọda bi o tilẹ jẹ ẹṣẹ ti Ọkunrin yi ṣẹ mu iku lọwọ ṣugbọn emi gẹgẹbi Ọba nyin dariji Ọkunrin yi nitori ko mọmọda ẹṣẹ na tani aba ba wi bikoṣe ẹniti o sin mọ fọkọ loru ti ko jẹki ilẹ mọ Iransẹbinrin mi ti o mọ pe ofin ni ti oru ni yio jiya rẹ Awọn ẹmẹwa re si da musọ wọn ni on ni iya na tọsi nitorina ẹso rọ sori igi ni doro ni ko do ki ẹ si pa ni apafọn to ba di irọlẹ.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA.

---

## Enyin Elegungun a bere foji

Anu ṣe ni lati gbọ lẹnu awọn ẹgbẹ Elegungun wipe, akọle oke iwe wa to jade ni ọjọ 22nd oṣu January 1962 wipe Egungun pa Egungun jẹ, eyiti o ba wọn ni orukọ jẹ, Nitori idi eyi, awọn Oniwe Irohin Imọlẹ bẹrẹ fun oji ki oji na si fo wa da. Aṣiṣe ni eyi

Ẹ jọwọ ẹnyin Ojẹs & Ọmọ Ọjẹ Improvement Society, A fi ori ba lẹ o.

Awa ni:-

OLOTU IROHIN IMỌLẸ.

## Itakun t'oni K'erin ma gunke

Lati Ọwọ:- ABIỌDUN AYANDA

Ọrọ mi ti ọsẹ yi tun dori ko dori o dori awọn abinu-ẹni ati awọn afẹ ki tẹni ma-ṣunwọn ti wọn njẹ Okeọra ati Iluju, ti wọn ṣi nfẹ tu ọru ti Ọlọrun Ọba funrarẹ di kalẹ wo. bẹ si ni wọn mọ daju wipe Ọdẹ ti o ba nsọ Ọlọrun, ori ẹgun na lo ma ku si. Asiko na wa de ti ọwọ Ọlọrun Ọba yio tẹ yin. nitoripe Ọlọrun yio ba de enia mu kosi iru aye iwakiwa ti ki gba oluwa rẹ, Gbogbo ọrọ rudurudu ti eti nfi ọwọ ara yin fa bọ lati nkan bi ọdun meje sẹhin, Ore nlaola ni eyi jẹ fun awa Oro ni ọjọ oni.

Ṣugbọn ni isisinyi ni owa yẹ ki ẹnyin ara Okeọla ati Iluju si oju yin si oke, ki ẹsi ṣe akiyesi Ojo (rain) ẹsin yin ti o su si Oke ọrun nrọ ojo na si ku diẹ, gbogbo ọna yowu ki esi gba, Ojo ẹsu na lati rọ le yin lori dandan, nitoripe bi Ẹlulu ba fa ojo ori ara re na ni rọ le lori.

Emi tun nsọ gbamgba-gbangba wipe kosi agbara ti ẹ le sa ti ẹ le fi gbe Ọja kuro ni Oro Lailai awọn Alufa ti ẹ gba lori ọrọ yi papa ko le ri agbara kankan sa lori ti ọja Oro, papa julọ mo fẹ fi irohin kekere yi to yin leti ohun ti oju mi ri nigbati mo lọ si Oro ni nkan bi ọsẹ mẹrin sẹhin Ọjọ ti mo de Oro bọsi ọjọ igba ekeji ti ẹ o na ọja atọwọda yin na, ni mo ba d a b a ati iya bi ọja yin na se nlọ si Gẹrẹ ti mo wọ ọja yin na bẹni mo ti awọn erọ diẹ nse girigiri ni apakan ọja na ni mo ba yara tẹ ẹsẹ mọ irin ki emi papa le mọ ohun ti o ṣẹlẹ. Bi moti debẹ ti mo si yọju si agbo ti w ọ n pa, bẹni mori obinrin kan ti on sọkun ọmọ ọwọ rẹ ti ọṣe alaisi ni arin ọja na oju temi ki si nibi ni mo ba yara fi ere si ẹsẹ mi ti mo si gba ọna Ile mi lọ.

E ko hari aiye lode ẹnyin enia wa gbogbo! Ọrọ buruku t o h u n t ẹ r i n! apẹrẹ buruku ni eyi jẹ, o si da mi loju wipe ọja atọwọda yin na yio gba ori buruku kẹhin ni, ni iwọn igbati ẹ ko ti fi irọwọ irọsẹ da ọja yin na.

Nipataki, "Ọga" gbogbo yin ti nfi fere mọto rẹ sọ igbẹhin ọrọ ti ọja yi fun yin, ṣugbọn ohun ti onsọ koye ẹnyin alaimọ kan enia rẹ.

Emẹta ni o ma nfi fere mọto na ke si yin. Ni akọkọ a sọ wipe "ỌRỌ AWỌN DẸTI; ni ẹkeji a sọ wipe ỌRỌ AWỌNKULẸ (Ẹnyin enia rẹ ni onfi eyi bawi, ni ikẹhin fere na ni yio wa fi ba ara rẹ wi, wipe "TCHUN DAGO Ẹnyin ẹ sa ma feti silẹ dada nigbati oba nkọja ni ọdọ yin, bi ẹba si sọ wipe ẹ ko mọ daju daju gbogbo yin nbọ wa mọ. Mo dupẹ aye ti ẹgba mi Olotu, ajinde ara yio ma jẹ, oju ko fẹraku o.

## Egbe Onisowo U. A. C. tun fi enia mejididinlogun si ipo Alakoso

Awọn ẹgbẹ Oniṣowo U. A. C. ni ilẹ Naijiria nipa ilẹle aṣa wọn lati fi awọn oṣiṣẹ wọn ti o ba yege ninu iṣẹ wọn si ipo alakoso ninu iṣẹ wọn ṣe ifilọ igbega awọn mejidinlogun ninu awọn oṣiṣẹ wọn si ipo Alakoso.

Awọn ti a ṣẹṣẹ yan wọnyi ni a mu lati gbogbo orilẹ ede Naijiria, eleyi si mu ki apọpọ enia dudu ti o wa ni ipo oyinbo ninu iṣẹ awọn oniṣowo U. A. C. jẹ ojilenigba

## SEBOTIMO (APA KEJO)

Lati Ọwọ:- FUNMILAYỌ KOFOWORỌLA.

O BẸRẸ LATI OJU EWE KAKUN

Nini-owo Ẹdakun ẹ da ọmọbinrin yi silẹ ni alafia, nitori eku to da eyi s i l ẹ ni ẹda e m i ni mo da ọran yi si arabinrin yi lọrun ẹbẹ ni mo bẹ nyin ẹdakun o, wọn ko tilẹ gbọ ọrọ ẹnu rẹ ti wọn fi so arabinrin yi rọ, nigbati o di ọwọ irọlẹ ni Ikọ-Ọba bẹ lori bi ori rẹ ti bọ silẹ gbo ni oyun inu rẹ fo yọ, ohun ti Ọ b a ati awọn ẹmẹwa rẹ lẹnu nipe lẹsẹkẹsẹ ni oyun na ti di ọmọkunrin gidigba gidigba pẹlu kumọ nla kan lọwọ.

Akiyesi:- Ẹ o ma ka apa kẹsan itan mi, oju ko fọ ra ku odigba kan na o.


## Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, biairọmọbi mba ẹ lọkan jẹ, tabi airiṣẹṣe lo nyọọ lẹnu, tabi o tilẹ nṣiṣẹ na owo iṣe na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo kọkọ bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ e. Kọwe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni ọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo ta lọdọ:-

AWORAWỌ

16, MỌLEYE STREET

P. O. BOX 166 YABA - NIGERA



BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TOINKI TITUN TI O ṢEṢE DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJEBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN ATI OBINRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣọ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Oni-bara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de ọkọn lọsan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹE-emi (breath) inu rẹ ko ba gunlẹ dara dara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJE" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọ d u n lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara lọjọ Otun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara re ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigba kugba "Arẹ" nigbakubga yio salọ patapata

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:

NIGERIN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278

**Waterloo Medicine Stores**
**8,Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OṢHOGBO

# FEDERATION OF NIGERIA THIRD DEVELOPMENT LOAN

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February/March, 1962. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966 - to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986 - to be repaid in full on 7th June, 1986.

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

*W. A. TIBBLE.*
*General Manager.*

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.


# DURO KO OGBON

O san lati gbọ ibawi ọlọgbọn ju ki enia ki o fetisi ọ r ọ aṣiwere lọ.

Maṣe yara li ọkan rẹ lati binu, nitoripe ibinu sinmi li aiya aṣiwere.

## Onisowo U. A. C. fun awon mejo ni anfani Eko ofe

OBẸRẸ LATI OJU EWE KEJE

Veronica, ọmọ ọdun mejila, jẹ ọmọbirin James Enimoh oṣiṣẹ labẹ awọn ọlọkọ oju omi ni Burutu ti o ti lo ọdun marundilọgbọn, yio lọ si ile ẹkọ giga our Lady's High School, Effurum, Warri gẹgẹbi akẹkọ ile. Lẹhin ti o ba yege ninu ẹkọ rẹ Veronica fẹlati ṣeiṣẹ alabojuto nile iwosan

Lẹhin ti aba fi anfani ẹkọ ọfẹ eyiti awọn ẹgbẹ onisowo miran ninu iṣẹ owo ṣiṣe ti U. A. C. ni ilẹ Nigeria pẹlu, apapọ anfani ẹkọ ọfẹ ni ile ẹkọ giga ti yio bẹrẹ ni ibẹrẹ ọdun 1962 jẹ mọkanlelogun.


# F. ma kawe Irohin Imole ni gba gbogbo, ki e si ma Polowo Oja yin sinu re


EMI AJẸGBORODAGBA NKI YIN KU ỌDUN KUYEDUN AṢEYI ṢAMỌDUN Ẹ O MAGBA DUN MI NI ỌSẸ TO MBỌ LAGBARA ODUDUWA


# Nigerian Ports Authority

## Invitation to Tender

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of the undermentioned scrap materials now lying on the Authority's premises: -

| Lot No. | Description | |
|---|---|---|
| 1. | 3 Coles Cranes Nos. 1, 3 and 4)<br>1 Ransome Rapier Crane No. 2 ) | ) as one lot |
| 2. | 1 Misg Crane K. 5000D | |
| 3. | 23 Lead Acid and Alkaline Batteries ex Craft | |
| 4. | 15 Easy Chairs )<br>9 Writing tables )<br>4 Mirrors on Stands )<br>3 Bed Frames )<br>2 Pairs Bed Ends )<br>1 Chest Drawers ) | as one lot |
| 5. | 22 Refrigerators Electric )<br>16 Cookers ,, )<br>7 Water Heaters ,, )<br>8 Ceiling Fans ,, ) | ) as one lot |
| 6 | 4 Typewriters Nos. 6A59064x6E05781x)<br>21400x481317) | )as one lot |
| 7 | 1 Lighter No. L.50 | |
| 8 | 1 Lighter No. L.54 | |
| 9 | 144 No. 44 Gallon Drums )<br>101 Carbide Tins )<br>40 No. 2 Gallon Paint Tins )<br>383 No. 5 Gallon Paint and Nail Drums )<br>78 No. 10 Gallon Grease and Snowcem Drums )<br>718 No. 4 Gallon Kerosene Tins ) | ) as one lot |
| 10. | Quantity of Steel ex Lightbouys etc. | |

2. The above items may be inspected on application to the following Officers of the Authority between the hours of 8 a.m. - 12 noon and 2 p.m. - 4 p.m. not later than Thursday, 15th March, 1962.

Lots Nos. 1 - 6 Senior Stores Officer, Apapa Quays
Lots Nos 7 - 8 Dockyard Manager, Apapa Dockyard
Lot Nos. 9 - 10 Senior Stores Officer, Apapa Dockyard.

3. A Copy of the Tender Form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, on payment of £20 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The completed Tender Form should thereafter be returned to the Secretary to the Authority in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL - TENDER FOR SCRAP MATERIALS" so as to reach him not later than 4 p. m. on Friday, 23rd March, 1962.

4. The successful tenderer will be required to pay for cut (where necessary), and remove the scrap materials at his own expense within 7 days of the acceptance of his offer, The deposit of £20 will not be refunded in any event to any tenderer, who upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for, and remove the materials as stipulated.

5. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. NoticeNo. 697.
2nd March, 1962.


Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS, 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Olotu E. A. Aden 24, Oliyide Street, Odu Abọrẹ MUSHIN.